

SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO




VOL. IX No. 529. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, JULY 20, 1957. KOBO MEJI (2)

## Ogoro awon Alhadji ku, die sonu lodun ni

MẸDINA. Ibosi laila, ila lahu; bi o ko lọ, yago, iku re e, dẹdẹigbo, lo gbojikan nigbati a gbọ irohin lati ilu Mẹcca wa wipe, ọgọrọ awọn Musulumi jake-jado igun mẹrẹrin agbaiye to lọ ṣe Hadji lọdun ni, bi awọn kan ti ṣke besi ẹsanri, bẹni awọn kan nkigbe inu rirun. Bi awọn kan ti nkigbe orugbẹ, bẹni awọn miran nkebosi otutu. Igbẹ ọrin, igbẹ ṣoro, Ilẹgbona ati oriṣiriṣi arun lo bẹrẹ si pa ogunlọgọ ninu awọn enia ni Hadji ti ọdun ni. A gbọ wipe, diẹ ninu awọn ti o lọ ṣe Hadji lọdun ni, lẹhin ti nwọn ti kirun tan, ni a kori mọ rara. Ki Ọlọrun ṣọ awọn yoku bọ wa sile.

Ọpẹlọpẹ yinyin ti awọn ọpọ enia nwọnyi di mọ ori wọn fun ọpọlọpọ ọjọ; iba ma ṣe bẹ ni, kisa mọfa iba ṣẹlẹ. Ọpọ ninu Alhadji ati Alhadja ti o ti de sile nilati tami fun ọjọ diẹ.

Diẹ ninu awọn Alhujaji ti o ti de ni Hadja Abadatu Samuel, ẹniti nwọn npe ni Mama Arose, Hadja Raṣidi Ojikutu, Hadji T. S. Calfos, Hadja Gbadamọsi ati Hadji Ajala.

(Wo iyoku loju ewe kejọ)




LYONS
ICE CREAM

EGB NLA (Big Vanilla Bars) 4d
EGB NLA ONI-ṢOKOLETI (Choc Ices) 6d
EGB TI O TO FUN Ọ ATI EBI RẸ (Family Bricks) 2/2d
EGB TI O TOBI-JULỌ (WONDER Cakes) 5/6d

Je Igbadun Re Loni

## Ọmoba Charles Se Ngoke Agba

Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Akọbi ọmọ fun Ọba Obinrin ilu Gẹsi ti nwọn npe ni Queen Elizabeth II, on ni ijọba Gẹsi aromi-royẹfun le lori nisisiyi lati fi j'oye ọba lẹhin ọla.

Ṣugbọn a ti agbọ kakiri lẹnu awọn alasọjẹ enia wipe nigbati o ba di ọmọ ọdun mọkanlelogun ni iya rẹ. Elizabeth Keji, yio gbe ẹru ijọba Gẹsi le lori, ki o ba le ri aye ma ba faaji rẹ niṣo.

Nisisiyi ọmọ na di eni ọdun mẹsan, o si ti bẹrẹ si fi oju si bi gbogbo iṣẹ ti nlọ si lọdọ iya rẹ. Ohun ti ọmọba yi fẹran ju ninu ẹkọ rẹ ni ẹkọ nipa apejuwe aiye, (Geography) Iru aṣọ ti ọmọba yi wọ nigbati o ṣe ase ọjọ ibi rẹ tokọja ni aṣọ Balmoral Tartan, aṣọ na ti a wi yi jẹ eyiti awọn ẹgbẹ jagun-jagun kan ma nwọ nilu Scotland.



PRINCE CHARLES

No. 73/S. 2/Vol VIII/471

**Ministry of Education, Western Region**

**Vacancy for Education Officer**

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Education Officer in the Adult Education Branch.

Salary: Scale A: £624 x 36 - 696;
£804 X £42 - 1140; £1,188 X 48 - 1,380.

For full particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 29, Vol 6 Notice 571 of 20th June, 1957.

Closing Date: Overseas Candidates: 13/7/57
All other Candidates: 20/7/57

# Hogan Kid Bassey



Ẹniti a nṣo yi ni ọgbẹni Hogan Kid Bassey lasiko ti on pẹlu olukọ re nṣe idanwo lati lọ koju ija pẹlu ọkunrin Abẹsẹ-kon-bi-ojo kan ti o njẹ Namia Barios, ara ilẹ Faranse.

Irohin ti a tun gbọ ni wipe lẹhin ti Bassey ti gba oye alagbara-julọ fun gbogbo awọn sawawu ẹgbẹ rẹ tan ni nwọn tun sọ wipe, ki ọgbẹni Bassey to fi ilu ilu Gẹsi silẹ, awọn fẹ ki o tun wa danra wo lẹkan si ni ọjọ 7th oṣu October 1957.

Ṣugbọn, awọn fẹ ki o mọ wipe, ija na ko nṣe lati gba oye re kuro, nwọn kan nfẹ fi pa a owo lasan ni. Nitoripe, nibikibi ti awọn oyinbo ba ti gbọ eruko Bassey pe, o fẹ ja, nwọn ko kọ iyekiye lati na sibẹ.




USED LORRY TYRES
PRINTING PLANT-
CLOTHING
ORGANS-BAND INSTRUMENTS
We export Anything.
ALDERSHOT WAREHOUSES LTD., POUND RD.,
ALDERSHOT, ENGLAND.

# Ere Football di ija ni India

INDIA Ijagboro bẹ silẹ nilu India ninu eyiti enia mọkanle-ladọta fi ara ṣeṣe ọwọ ọlọpa si tẹ enia merindin-lọgọrin lati ba wọn ṣe ẹjọ.

Ohun ti a gbọ wipe, o fa ijagboro na ni wipe, awọn ẹgbẹ elere Football meji lọ ba ara wọn ṣe ariyanjiyan wipe, ojoro ni ala ojuto ere ball afẹsẹgba na ṣe ki ekini to pa ekeji layọ.

Ekeji si dahun wipe, ṣe awọn ẹgbẹ kini na lokọkọ da ojoro silẹ ti alabojuto si sọpe on ko ri.

Nibiti nwọn gbe nsọrọ yi, ayafi Paa! Poo! eti gbigba ati ẹsẹ fifilu ara wọn. Nwọn ja lati ibiti nwọn ti lọ gba bọlu de arin ilu, gbogbo mọto ni lati duro fun wakati meji nitori awọn onija awọnyi, werewere, ilu ti da si meji, oluku-luku ngbeja awọn ngbeja awọn enia tirẹ. nwọn yinbọn, ṣugbọn igi, kondo ati akọ abara ni nwọn fi ṣe ara wọn leṣe.

No: 73/S.2/Vol, VIII/478.

## Co-operative Department, Western Region
## Vacancy
### For Accountant

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to a post of Assistant Registrar (Accounts) in the Co-operative Department. The successful candidate will be posted to the Western Region.

Salary: Scale B. 1, 2, 3. (Gorsuch) starting at £600 per annum.

For full particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 31 Vol. 6 Notice No. 613 of 4/7/57.

Closing Date: For Candidates in the U.K. 21/7/57.
All other Candidates 31/7/57.

No. 73/S. 2/Vol VIII/478.

## Medical Department, Western Region

### Vacancy For Health Sister.

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the vacant post of Health Sister in the Western Region Medical Services.

Salary: Scale N. 4 (i.e. £570 x 24 - 618;
£690 x 24 - 714; £744 x 30 - 864) plus £60.

For full particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 31 vol. 6 Notice No. 614 of 4/7/57.

Closing Date: For Candidates in the U.K. 24/7/57
All other Candidates 31/7/57.

No. 73/S.2/Vol. VIII/478.

## Ministry Of Education, Inspectorate Division

### Vacancies For Senior Inspecting Assistants.

Applications are invited from suitably qulified candidates for appointment to the post of Senior Inspecting Assistants who are are experienced teachers and supervisors with organising ability, in the Ministry of Education, Western Region, Ibadan.

Salary: Scale A: £624 x 36 - 696;
£804 x 42 - £1,140

For full particulars and method of applications see Western Region of Nigeria Gazette No. 31 Vol 6 Notice 615 of 4/7/57.

Closing Date: For candidates in the U.K. 20/7/57
All other Candidates 31/7/57.




# Ogagun inu Oko



Baiti a nwo ninu aworan yi ni Ogagun ati alaṣẹ agba paraki ninu ọkọ Ogun nla kan ti a npe ni H. M. S. Ceylon. Orukọ ogagun na ni Geofrey Robson. Ọkọ ure ni Ijọba Gesi yan lati maṣe asọde oja omi okun lati ilu Londen si South Afrika.

Lasiko ti o wa si ilẹ Nigeria, o gba gbogbo awọn ara ilu Eko laye lati wa yẹ inu ọko rẹ wo, gbogbo awọn onlwe irohin ni nwọn fi gbogbo aṣiri inu ọkọ na han, nwọn si ṣe alaye fun wọn nipa gbogbo ohun ti nwọn here.

# Odun jamboree fun gbogbo Awon Scouts



Lọdunni ninu oṣu August lati ibẹrẹ oṣu na titi di ọjọ kejila ni gbogbo awọn ilu ti o nsọ ede Gẹsi ylo ran awọn Scouts lati ilẹ wọn lati lọ ṣe aṣoju ilu wọn ni ibikan ti nwọn npe ni Chigwell nilu Oyinbo nibẹ ni ojutaiye ti gbogbo awọn Scout agbaiye, olukulaku ylo ma ṣere idaraya ti ilu rẹ fun gbogbo enia wo,

Nlau aworan oke yi ni a gbe ri awọn Scout ilẹ wa yi nibiti nwọn gbe nse ere idaraya jru eyiti nwọn o ṣe nigbati nwọn ba de ilu Oyinbo. Awọn ọdọmọkuarin lo ṣiwaju awọn ọdọmọbinrin lo gbẹhin

In gayama, gayama in fubu,
Yabo, yabo, yabo, in fubu.

## Awure

Inmnurin lawo Inuuurin.
Alakiaṣa awo ilasa,
Lo da fun alayun Ayunrẹ
Ti gbogbo aiye rin gbindi mọ.
O to ge! ki nwọn fẹran mi
Gbeja lẹja o ma yọmọ mi
Gbeja, Ire ko loruko
meji Ire ni ire njẹ gbogbo ara ni Kẹfun-kefan fi aka aja.

SECOND-HAND CLOTHING:-

| | |
|---|---|
| Women's Long Overcoats | 2/6d. |
| Women's Short Coats | 1/6d. |
| Women's Dresses and Frocks | 1/- |
| Women's Skirts | 1/- |
| Men's Overcoats, | 6/- |
| Men's Raincoats, Cotton and Gabs mixed | 2/6d |
| Men's Jackets | 2/- |
| Men's Waistcoats | 6d |
| Men's Felt Hats | 1/- |
| Police Helmets | 1/- |

Prices quoted ex Warehouses C.I.F. charges extra.
Wholesale quantities only
Immediate attention, Write for full prices list. Organs £10 Radiogram £10, Pianos £10 Typewriter £10. Sewing Machines £10.

H NEWMAN & CO. (MERCHANTS) LTD.
88/92, ELIZABETH STREET,
MANCHESTER, ENGLAND.

# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 529. LAGOS, SATURDAY JULY 20, 1957


## Ajaga Afikun Owo Ori Ko Ni Le Wo

Ni ẹrinkan si a fẹ lati ki awọn ikọ wa ti o lọ si ilu Oyinbo lati lọ ba wa ṣe eto atnoṣe ilu wa ti a npe ni Naijiria ku abọ. E ṣe-ẹ si ku iṣẹ ilu.

Gẹgẹbi irohin eto ilu na ti a gbọ, ti a si tun ri ka, a gbọ wipe eto wa nilẹ fun lati gba iṣẹ jagunjagun (Military Force) lọwọ Ijọba Gẹsi ninu ọdun ti o mbọ yi. O dara bẹ, ṣugbọn a fẹ ki a tun gbe ọrọ na yẹwo daradara bi eto bayi ko ba tun ni fun awọn ara ilu ni afikun ajaga owo ori apapa-ndodo.

Awọn Yoruba ni "Igi ganganran ma gun mi loju okere ni a ti ma nsọ" owe ni o. Bi a ba tun ọrọ yi yẹwo daradara, a o ri wipe ọrọ a ndi ara ija kọ ni ohun o ba wa nisisiyi. Ko si ọta nita ti o nle ri wa sinu-bi ko ṣe iṣẹ to nṣe awọn ara ilu wa pẹlu ebi (ọgaja fọwọ m'ẹkẹ) ti o npa ogunlọgọ wa lojojumọ.

Awọn alamu-le-gbe wa, awọn Gẹsi to ni ọmọ Ogun, ti o si ni ọrọ ṣọja fi ṣe, ko sọ wipe o su awọn lati ma nawo idi rẹ. Kini a ngba lọwọ wọn fun? A tilẹ le ṣe eleyi lẹhin ọdun mẹwa ti a ba ti gba ominira wa.

Ajaga owo iṣẹ ti awọn jagunjagun ki iṣe yẹyẹ o.

---


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orişirişi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Şile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Tani Akoda Ati Aseda?

Lati Ọwọ Ẹsọ Ikoyi

Akọda ati Aşẹda ni awọn enia meji ti o kọkọ lọ kọ iṣẹ Babalawo lọdọ Ọrunmila, lẹhin ti awọn meji nwọnyi ti kọ Ifa pari ti nwọn si ti lọ ni Araba, ati Oluwo tun wa kọ Ifa lọdọ Ọrunmila, Ẹniti o tun wa kọfa lẹhin awọn nwọnyi ni ọkunrin kan ara Ado ti npe ni Arẹgi-lado, on na lo si di Awo ilu Ado.

Ọbalufọn lo tun wa kọ Ifa lẹhin na, ṣugbọn o tun fi iṣẹ Ahunṣọ kun iṣẹ Awo tirẹ. Eyi ni idi rẹ ti awọn Ahunṣọ ṣe njuba rẹ nigba gbogbo. Ọkunrin kan ara Ijẹbu lo tun wa kọ Ifa lọdọ Ọrunmila lẹhin Ọbalufọn, on ni a npe ni Babalawo Elewuru ti o fi ẹmi ara rẹ gba ilu Ijẹbu la nigbati Olọşa nfẹ gbe wọn mi.

Awurela tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Awo Ọrunmila, on lẹniti o gba awọn Babalawo la nigbati Ọba Ijẹbu nfẹ pa wọn. Aşẹgba tun jẹ Babalawo kan ti o kọ iṣẹ awo lọdọ Ọrunmila on ni Oluwo fun awọn Ẹgba. Ajitare jẹ ọmọ awo Ọrunmila on si ni Babalawo wọn ni Ekiti Ẹfọn.

Ogun jẹ Alagbẹdẹ ṣugbọn ọmọ awo Ọrunmila lo jẹ, Ifa Oloju mẹrin l'o kọ. Alagbara niṣe, on lo si tẹ ilu Ire do. On lo si kọkọ fi irin şişẹ nilẹ Yoruba.

Ọsanyin tun jẹ ọkan ninu ọmọ awo Ọrunmila, Ifa Oloju mẹrindilogun lo kọ.

Nigbati egbo da a ti ko ri alafia ni Ọrunmila ba fun laşẹ ewe jija, lati fi şanu rẹ. Orişa Sungbo ni obinrin Alarẹn kan ti o lowo lọwọ ti ko le na, on lo wa eredo yika gbogbo ilẹ Ijẹbu ati agbegbe rẹ lati ma fi şe iranti rẹ titi. Nitoripe ko bimọ. Sare tabi iboji rẹ mbẹ ni Oke Ẹrimu tabi ilu Ijẹbu Ode.

Ẹlẹgbara ni ọkunrin lile kan ti a npe ni Eşu, şugbọn ko nşe on ni nwọn npe ni Eşu Ọdara Ọbanta ni ọba Alade kan ti o ti jọba nile Ifẹ Ọyẹlagbo, lati Ifẹ lo si wa tẹ Ijẹbu Ode do lasiko Ọba Ọwa Ọşin. Iranlọwọ ala lo jẹ fun Ilu Ijẹbu lasiko ogun.

Nigbati Ọbanta dagba daragbo, nşe nşe lo wọlẹ lọ laye ni ibi aye kan nilu Awa.

Odudugbunudu ni Babalawo alagbara kan ti o wa fun ọba Oşemawe ni Ondo; o si şe gudu-gudu meje fun ọba na lasiko ogun ilẹ Yoruba. Babalawo alagbara kan ti a npe ni Olumọ lo tun şe kisa fun awọn ara Odo Imọri on pẹlu Babalawo kan ti a npe ni Aşade şe akan silẹ Ijẹşa Laberinjẹ ati Jingere lo tun şe patẹki ti a tun le da orukọ wọn.

Şọpọna jẹ ọmọ bibi inu ọba Ọranyan. Yemọja si ni orukọ iya rẹ, ni ile Ifẹ Ọyẹlagbo ni a bi si. Iwa buruku ati Iwa ika wọpọ si ọwọ rẹ. Ọkunrin yi l'ẹniti o kọkọ wa egbogi Ilẹgbona ni awari lati ma fi şeka fun ọmọ enia, ko si loju anu. Iwa yi lo sọ ọ di ọkan ninu awọn Irunmọlẹ. Ọranyan nigba aiye rẹ, jẹ jagun-jagun ati Ọlọdẹ. Ọdẹ lo şe titi o fi de Ọyọ ile ki o to tẹ ẹ do. On na lo si kọkọ jọba nibẹ. Ọpa rẹ ti o fi silẹ ni Ifẹ şi mbẹ nibẹ titi d'oni.

Yemọja lo bi Dada Awuru-yalẹ-yagi-oko, On na lo bi Şango jẹnigbo, jẹniju ati Şọpọnna. Şonge jẹ Ologun ati Ọlẹdẹ, bi o ba nsọrọ ẹfin a ma jade lẹnu, leti ati loju bi eyiti o nmu siga. Ọya jẹ iyawo Şango, o si jẹ ara ilẹ Tapa. o jẹ lagbara ati Ologun, Ọşun jẹ gbajumọ ara ilẹ Ekiti Ẹfọn.

## Jagunjagun W'olu, E Fi ... ra Bale

Ọkunrin kan ara ilu Numa ba iṣẹ Şọja lọ si ogun Jamani ti o kọja lọ yi, nigbati ogun si pari tan ti gbogbo awọn jagun-jagun npada bọ wa sile, awọn obi rẹ ko ri

(Wo yoku loju ewe karun)

### JAGUNJAGUN W'OLUJ E FI ARA BALE

(O bere loju ewe kerin)

ki o pada bo wa sile; nibiti awon enia re gbe nse Iwadi nipa re, ibe ni nwon ti gbo wipe, o ku si oju ogun (Died on active Service).

Baba ati iya omokunrin ti a wi yi ni owo lowo jojo inu won si baje, nigbati nwon gbo pe omo won ku soju ogun. Toi awon ni lati gba fun Olorun.

Ni odun 1953. ni omokunrin kan ti o ngbe edugbo kanna po pelu eyiti o ku soju ogun, ti o je wipe ise awon ti o mba oko oju omi kakiri ni on paapa nse lasiko ogun, ba oko awon oyinbo Barber Line lo si ilu New York.

Bi o ti nrin kiri nigboro ilu New York lojo kan, beni o pade okunrin ti awon so pe o ku soju ogun yi, nwon ki ara won tan ni okunrin oloko (Seaman) wa bere lowo re wipe, kiloti rin ki o to de ihin ?. O si dahun pe, okunrin kan enia dudu ara ile Amerika (Negro) lo mu on wa sibe. On si ti ri ise atata se, ati pe lowo lowo yi, egbarun poun ko jamo ohun kan loju on. O wa fa iwe owo yo ninu ape (Cheque) o ni ki nwon fun baba on ati iya on ni ogorun poun (£100) ki baba on mu adota poun ki iya on mu adota, o wa fun seaman yen ni ogun poun pe tire nuni. O tun fun ni (Visiting Card) pe, ki o mu fun iya on nwon o ri ibiti o ngbe nibe, ki nwon kowe si on pe, nwon ri owo gba.

Nigbati Seaman de'le, o jise fun awon obi soja yi. O si fi owo le won lowo; o si so iye to fun on papaa. Gere ti nwon gba owo na tan, ni nwon te waya pada pe nwon ri owo gba. Lojo kanna lo tun ranse pe, on pelu iyawo ati omo on mbo wa be iya on wo. Lojo ti o de nina odun 1954, nse ni gbogbo ilu nro giri.

Lehin ti o ki awon obi re tan, o ni on ko le gbe ilu Nuna, on yio pada si New York, ki awon obi on kalo Baba re ko. Iya nikan lo balo.

## AKIYESI PATAKI

**Enikeni ti o ba fe ra Iwe irohin Eleti - Ofe Ki o lo si Idi moto, Ogunpa, tabi lodo Asoju wa, ni 107, Oke Padi, l'egbe Sosi Aguda nilu Ibadan.**






Awon gbajumo enia gba . . .

E seun — Emi yio ra Star si. Bia na ma a nfun ni ni itelorun po! Gbogbo awon ti awon wa be wa wo ni nwon gba pe STAR BEER dara pupo, o nwo bi titun, o si dara gan an ni. O tun nfe omiran bi ?

OTI STAR

l'o je eyiti o dara ju!



STAR BEER dara po. Oti ti o nwo lwe titun ti nwon si fi aroja ti yio ma 'a fi ra soke pe ni. Awo re wo ni l'oja. Oorun re gbadun pupo. Awon ara-ile ti o dara pe ni awon fi npo aroja re po.



Beni Sammy Sparkle wi.

# Ojo Ariya Awọn Jagun-jagun Ni Zaria

(Lati ọwọ Ola Osatade)

Ni aipẹ yi nibiti mo gbe nwa idi ọrọ awọn jagunjagun kiri ni mo pade ogbologbo ṣoja kan ti o ti ṣe ọdun mejilelogun ninu iṣẹ ologun. Mo bi lere wipe kini ere ti o ri gba ninu iṣẹ yi ti o fi joko pẹ nibẹ to bayi.

Ọrẹ mi, ogbologbo ṣoja yi woke, o tun wo ilẹ o ni "iwa lo ju ninu iṣẹ ṣoja, enikẹni ti o ba fẹ sin ilu rẹ tokan-tokan, o ni lati le jagun fun".

Ẹ wa tẹle mi ka lọ sibiti a gbe nwo iyege ere awọn ṣoja ni ilu Saria titi de Ibadan nile Oluyọle, nibiti ṣoja ti nkọ ija igboro, bẹni ija igboro yi ni oro ara Ibadan.

Ọsẹ meje ti pe ti o ti wa ninu a nkọ iṣẹ jagunjagun ni Zaria, o wa di owurọ ti ẹ ni lati ṣe ere iyege pẹlu igba awọn ṣoja ẹlẹgbẹ rẹ.

Ija yi dun wo pupọ lọdọ awọn ṣoja, wọn si ma nfẹ ki ọpọlọpọ alejo wa ri ere ọjọ na. Awọn ṣoja ti o fẹ ṣe oluyege iyawo tete ji ni owurọ kutukutu ọjọ na lati di ihamọra wọn. Ewu wọn a mọ toni-toni oniṣi ẹwu wọn a ma dan mọna-mọna.

O dun mi wipe ko si aye tobẹ ni, emi na ko ba kọ ọkan fun yin ninu orin iyiri ti awọn onilu (military Band) wọn ma nkọ ti wọn ba nto wọn lọ si iwaju awọn ogunna gbongbo jagunjagun ọga wọn lati wo bi wọn yio ti ṣe ete-ijade wọn.

Ninu ere ka rin k'a ma yan yi, wa tun to siwaju awọn enia lati ṣe iburu wipe iṣẹ jagunjagun ti o wọ yi wa ma ṣe otitọ ninu rẹ, o ko si ni gbabodi si oba ilu ti o je ọmọogun fun.

Alaṣẹmọ ti bi ọmọ rẹ tan alaimọ ijo jo ku si ọwọ rẹ, ni oro awọn ṣoja nigbati wọn ba ndagbere ilun awọn ọga ti o kọ wọn fun ọsẹ mejidinlogbọn. Ọrọ pọ ninu otito ti wọn nkọ fun idagbere yi, o si mu ori enia ya jọjọ. Wọn a ma gbe ẹsẹ nikọkan, wọn a si yi oju sibi ti awọn ọga na gbe duro si lati ki wọn wipe, "O d'gba, o ṣe".

Igbadun ọkọ dun lati ma wo papa ilẹ Naijiria ati odo Ọya ti awọn Oyinbo npe ni River Niger. Ti o b wo odo Ọya yi wa niran itan Ajagunmolu kan ti a npe ni Lọdu Lugadi (Lord Lugard). Ọgbẹni Oloye ti mo fi enu kan yi ṣe bẹbẹ nipa iṣẹ jagunjagun ati ọrọ iṣelu ni ilẹ wa

Oruko Oloye Lọdu Lugadi yi ko le parun nilẹ ..a lailai nitorina ni a ṣe sọ ile ti awọn oṣelu npajọ si ni Ile Lugadi (Lugard Hall) ni Kaduna. Emi p pa mọ Oloye yi ni ologun pataki nigbati mo nlọ sile ẹkọ ni ọdun 1915. On si ni Gomina ti mo kọ mọ nigba ewe mi. Nje iwọ na ko mọ nisisiyi wipe Oloye yi Ajagunmolu ni nitotọ; lati inu iṣẹ jagunjagun o di oṣelu pataki (prominent statesman) Awọn Olorogun ni iru enia bẹ ni awọn nwa ninu awọn ọmọ wa ti yio mu ilu wa duro ṣinṣin lẹhin ọla. Ọrọ pọ nibẹ o.

Nigbati o ba ti de ilu Ibadan, ni ẹkan ninu ọdun, o ni lati ba wọn lọ jagun ninu igbo gẹgẹbi enipe o nba awọn ọta ja. Ẹ le fi ẹsẹ rin bi busọ marun tabi mẹfa ki ẹ to ba mọlẹ ni ibuba ninu igbo pẹlu ibọn lọwọ. Emi ti mo nkọ iwe yi ti ri wọn bi wọn ti nṣe ni ibikan ti a npe ni Olokemeji. Ti o ba ri wọn iwọ na a ṣe bi wọn wa loju ogun ni.

Ma gbagbe wipe bi o ba ti ṣe mọ ogun inu igbo yi ja si ati pe bi iwa rẹ ba si ti tun dara to, bẹni wọn a ṣe ma gbe ẹ ga si iwaju si, iwọ na si ndi ọgagun lọ niyen. Wa gba okun si apa, wa tun gba medali si aiya. A ki di jagunjagun ju bẹ lọ.

Ti o ṣe eleyi tan wa gba isinmi lọ si ilu rẹ lati ri awọn ara rẹ nibikibi ti wọn gbe ti bi ọ. Wọn a san owo ọkọ rẹ ni talọ ati abọ ṣugbọn "adimeru" miran ti o ba tun ni bi ti owo ọkọ iyawo rẹ, wọn ni awọn ko ni ọwọ ninu iyẹn.

Awọn jagunjagun ko wipe ki o ma niyawo atipe ki o ma bi ọmọ. Owo kan tilẹ wa ti nwọn ma nsan fun ni lori iyawo ati ọmọ ti o ba ni, ṣugbọn wọn ko ni ki a di iyawo lọ soju ogun.

---

# Barika re, Oke Arafa ti o gun

Ogunlọgọ awọn Alhadji to lọ lati ilẹ Nigeria lati ṣe Hadji fun Ọlọrun ni nwọn ti bere si fo bi ẹiyẹ pada sile.

Ni apa ilẹ awọn Hausa, awọn enia to jẹ gbajumọ ti o ti lọ ba wọn ṣe Imura Hadji, nwọn gun ori oke Arafa, ti nwọn gun Mina, ti nwọn si tun gun ori oke Jabali Toro, ti nwọn si ti pada de ni awọn enia bi, Alhaji Ahmadu ti o nṣe Sardauna Sokoto.

Idi rẹ ti o ṣe tete fi wa sile bẹ ni wipe, o ni lati wa pade Iya Ọba Gesi, ti o fẹ gba ilu rẹ kọja nitoripe, on ni prime Minister fun ilẹ Hausa, ajeji ko si le wọ ilu ki onilẹ ma mọ.

Awọn Alhujaji ti o tun ti pada de ni Alhadji Abu Bakare Tafawa Balewa ti o nṣe Minister of Transport, Muhammed Ribadu, ti o nṣe Minister of Power Alhadji Isa Kaita, Alhadji Adegoke Adelabu, ati



ALHADJI ADEGOKE ADELABU

Alabadja Hadijat Gbadamosi Hadji Mualiu Tijani, alhadji Ekemọde, eniti a ti ngbọ ohun rẹ ninu ẹrọ gbohungbohun lasiko igbati o ba npe wasi.

Opopo Meka me roro, Aljanna nile wa.

Gbogbo awọn enia nwọnyi lo ti de Meka, ti a wọ a de Medina, awọn fi oju ri ibiti Ibrahima ti ngbe, awọn fi ẹnu kan Oke Kaabba, nwọn si de ile Olorun, ẹṣẹ wọn parẹ.

---

# Tisa To Ku Mu Awolowo Ni Babasinku

IBADAN, Ni Ibadan ni ọsẹ ti o lọ ni a gbọ wipe ọdọmọdekunrin ara ilu Ibini ti o nṣe iṣẹ Tisa olukọni nitiruko rẹ njẹ Edward Irhoboeye ni ẹniti o pa okunso ti o ku ninu ile mehaya ti o ngbe ni Oke-Ado lọna Ijẹbu.

Tisa Edward yi ni a gbọ wipe ki o to ku o ṣe iwe awisilẹ ti a npe ni WILL ni isisiyi ninu eyiti o wipe on yan Alakoso Ijọba Iwọ-Orun, Ọlọla Ọbafemi Awolọwọ ni Babansinku - o la wẹwẹ bi wọn yio ti ṣe pin gbogbo nkan ini on ninu awisilẹ ti a ri ni apo rẹ.

Ọmọ ọdun mẹrindilọgbọn ni arakunrin na, ni ilewe ti a nkọ awọn olukọ (Tisa lẹhin ọla) Ibadan Government Training College ni o nṣe iṣẹ. Nkan ti o mu ṣe iṣẹ buruku yi ko ye wa, ṣugbọn a gbọ wipe o kọ sinu iwe wipe aiye yi tilẹ su on patapata.

Kere o!

A ti ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.

# Okunrin akorin kan gba ikuku lenu

AMERIKA. Okunrin kan, enia dudu, ara ile Amerika, lo pe awon enia jo wipe, on fe korin alarabara kan fun won gbo, awon ara Amerika sa feran nkan bawonni.

Ni ale ojo na, ile kun, ona bo, nigbati o se ni okunrin akorin na bere orin yi ni kiko, nse ni gbogbo enia dake ti nwon nfi eti si orin na, nitoripe o dun mo eti won.

Bi okunrin na ti nkorin yi lo, lojiji, beni okan ninu awon ero iworan sare dide, o fo si ori ibiti nwon ti nsere, o si gbe ikuku (ese) kan le eniti o nkorin na leun, iran di meji.

Nigbati ariwo poju, ni awon olopa ba wo'le opelope won lo gba okunrin akorin na sile. Nigbati omo akorin na ri ohun ti o sele si baba re, o yara bo sori ibiti nwon ti nsere, nitoripe on na ti mo orin na, o si mba orin kiko na nlso. Nwon mu okunrin elese na lo si kotu.

Awon olopa se itoju enu akorin na, nwon si mu lo sile alaisan ti o wa nitosi. Ere ti omo na se fere dun ju ti baba re lo; nse ni nwon nho, ti nwon npatewo. Awon ero iworan na to egba a.

# Alapara Ibadan nki yin o

OKE FOKỌ
Ibadan

O ya mi lẹnu pupọ wipe ko pẹ ti mo ko ara mi jade bi ọmọ ijọ mẹjọ, ọpọlọpọ enia ni o ti kọ iwe si mi ti mo si ti ri gba lati ọdọ Aṣoju Eleti-Ọfẹ ti o wa ni 107, Oke Padi, nilu Ibadan.

Eyi ti o pa mi l'ẹrin pupọ ni eyi ti mo ri gba lọdọ ara kunrin kan ti o ni on njẹ Igbalaiye. Ọmọ Ibadan ni-o sọrọ nipa ọdun egungun ni ilu Ibadan. Iwe rẹ niyi:–

"Alagba,

'Jọwọ ẹmi ko fi ṣe ọyaju o, ṣugbọn mo ro wipe ọmọ Ibadan niyin ?. Ọrọ ti mo fẹ sọ yi, ẹ ma jẹ ki o bi yin ninu o, Ọmọ Ibadan ni emi na.

Kilo ṣe ti o fẹ dabi ẹnipe ko ajọṣẹ papọ nilu Ibadan ?. Ẹ jẹ ki a ti ibi iṣana kiye si etu-ọdun egungun ni a nṣe yi, ko si ibikan pataki ti egungun npejọ si lati pa idan ni ilu wa.

Ko si ilu ti egungun nla ko si nilẹ Yoruba, ṣugbọn wọn ni eyi ti o ma npa idan fun gbogbo enia lọkunrin ati lobinrin wo.

Nigbati mo wa ni Abẹokuta, mo wo awọn egungun ni Ijaye, ni Itoku ati Agọ owu. Tani ninu agbalagba asiko yi ti o le gbagbe Ajofan-oyinbo tabi Ayelabọla ?

"Mo tun ba wọn ṣe ọdun egungun ni Ijẹbu ati Ọyọ ri o. Ẹnyin ara Ibadan, igba ma si ni aiye o.

"Kiloṣe ti egungun wa, "Alapansanpa" ṣe sọ wipe on ko jade mọ ? Eyi fẹ dabi aṣeju o. Ti o ba jade wọn a tẹle bakanna bi ti atijọ ṣugbọn tori ki a fi ma na enia ni gbogbo ilu kọ.

"Alapanṣanpa nikan kọ ni mo nba wi-gbogbo ẹnyin ọlẹ ilu wa ni ọrọ bawi. Ẹ pe ara nyin jọ ki ẹ fi ọrọ ṣe ikan, ki nkan idi e wa ma ba parẹ".

Ọrọ ọrẹ mi "Igbalaiye" niyi, ẹnyin ara Ibadan, ẹ fi ṣe ọgbọn. Eyiti Alapara Ibadan gbọ niyi o.

No. 73 / S.2/Vol. VIII/475

# Public Works Department Western Region

## Vacancy For Storekeeper (General)

Applications are invited from suitable qualified candidates for appointment as Storekeeper (General) in the Public Works Department, Western Region on pensionable or contract terms.

Salary: Scale C(T) 3,4, i.e., £774 x 30 – 864; £900 x 36 – 972; £1,014.

For full particulars and method of application see Western Region or Nigeria Gazette No. 30, Vol 6, Notice 597 of 27th June, 1957.

Closing Date: For overseas Candidates: 15/7/57.
All other candidates: 22/7/57.

No. 73/S. 2/Vol VIII/475

# Ministry of Education Inspectorate Division

## Vacancy for Assistant Inspector of Education

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Assistant Inspector of Education, Ministry of Education, Western Region Ibadan.

Salary: Scale A(U); £1,188 X 48 - 1,380 plus £270 Inducement Addition on salary not exceeding £1,284 and £300 on salary of £1,285 and over where applicable.

For full particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 30, Vol 6 Notice 589 of 27th June, 1957.

Closing Date: For overseas Candidates: 25/7/57
All other Candidates: 1/8/57

## ORIN YORUBA

Maṣe na'mọ Balogun
Bi mo ba na'mọ Balogun
nkọ?
Idagiri a wọ ilu
Ẹsẹ giri-giri a gbode
O ti nna'ra wọn ri
Ko si tun ṣ'ara wọn mọ
Ọrọ bẹ l'o ndun wọn
Lasan, lasan ni inu mbi
wọn.

"The English Association of Accountants & Auditors. The English Association of Estate Agents & Valuers. The English Association of Secretaries.
Founded 1941. Membership on Professional Experience, or Certificate with Reputable Schools Colleges, Universities"
9, Charles St. Newport, Mon, Eng.



No: 73/S.2/Vol, VIII/471.

## Lands Department, Western Region.

### VACANCY FOR LANDS OFFICER

Applications are invited from suitably qualified candidates; who preferably should be between the ages of twenty-five and forty, for appointment to the post of Lands Officer in the Western Regional Lands Department.

Salary: Scale A £624 x 36 - 696;
£804 x 42 - £1,380 plus

Inducement Pay where appropriate Point of entry to be determined according to qualifications and experience. Candidates with legal qualifications and at least 2 years post-call experience shall be eligible to enter the scale at £804 per annum.

For full particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 29 Vol 6 Notice 566 of 20th June, 1957.

Closing date: For Overseas Candidates 8/7/57
All other Candidates 15/7/57.

## ANFE ASOJU

A nfẹ Aṣoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ọfẹ lati fi kun awọn Aṣoju wa si awọn ilu ti a darukọ si isalẹ wonyi:-

Abẹokuta, Ijẹbu-Ode, Ijẹbu-Igbo, Ile-Ifẹ, Oshogbo, ati Port Harcourt.

Ẹ kọwe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ, 28, Kọsọkọ St. Lagos.


# M.B.T.

## (MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T. dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sáré. òyì pọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀. Àlá burúkú wọ'gbó. àìlèsùn r'ẹ̀hìn-ẹ̀kùn. M.B.T. tògùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'ìkan, amú ni yàgbẹ́ bi ọ̀kùn, amú ni kọ bi àkèré. Abíwẹ́rẹ́ fábọyún, agbàjẹ́dé pawọn abiyamọ. Alọ́n-dúdú, ẹ̀ṣẹ̀-wíwú ati àìyà-jíjá ko si péníílì wọn. 4/6 pẹ̀lú 1/6 owó-gbé.

ARADAN STORES P.O.Box 2. EBUTE-METTA.


## Awon Alhadji Ku

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Wo oju ewe kẹfa Iwe wa ọsẹ yi fun irohin awọn ti o ti pada de sile lati ile Arabia. Awọn ọmọ wa ti anu ṣe wa jojọ lati gbọ irohin iku wọn ni Alhadji Nọsiru Oroyinyin ati Hadji Mustafa Lawal nita Akanni.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo ẹnyin Aṣoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Ọya, nilẹ Ibo, l'oke Okun ati a ju Oyinbo wipe ẹnikẹni ti ko ba fi owo ranṣe, ao ko orukọ rẹ fun Lọya Eleti Ọfẹ, ao ba ṣe ẹjọ ao si gba owo irin aṣẹ lọwọ wọn.

OLOTU


# Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



*Read this list of popular titles*

JZ 6077 - Omosola Savage/Igba Laiye
6078 - Aiye Akamara/Iwa Rere Leso Egia
6079 - Gbo Adura Wa Baba/Irele Lo Laiye
(Roscy Show Mambo Orch)
6080 - Gba Wa Lowo Ota/Iberu Olorun - S. O. A. Ledipo and His Koranic Group
6082 - Olomo Lo Laiye/Feso Jaiye
6083 - Shogbolo/Weinngton
Ade-Ade & His (Juju) Orchestra.

JZ 6088-Owo Lowo Agbara Ko/ Abiba Alaso
" 6087-Ori Lo Yomi/Saka Ilorin
Aminu Olarjibigbe & His (Sakara) Band
" 6089-A Gbere Wa De/Awon Kokokoko-
Taibus Abuna & His (Apala) Band
RJZ 100-Ma Pami/Zambesi (In Afro-Cubol)
RJZ 101-Bowo Ba De/Adaku (Ibo)
RJZ 102-Ma Doyinbo/Igbnem Iwem (Itsekiri) (Ibo)

*Sold by all the best stores*

"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow label* RECORDS

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23370